# KERESIMESI KIN-IN-NI

## Matteu 2:1-23; Luku 2:1-20

## ẸKỌ 417 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Jesu ni iwọ o pè orukọ rẹ̀: nitori on ni yio gbà awọn enia rẹ̀ là kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn" (Matteu 1:21).**

**I Ibi Kristi**

1 A bi Jesu ni Bẹtlẹhẹmu, Ilu Dafidi, Matteu 2:1, 5, 6; Luku 2:1-7; Johannu 7:42; Mika 5:2

2 Ipin Jesu laye rẹlẹ̀, kò si nilaari, a bi I ni ibujẹ-ẹran, Luku 2:7, 12; Orin Dafidi 2:7; Isaiah 9:6, 7

**II Ibẹwo Awọn Oluṣọ-Agutan**

1 Ogo Oluwa tan yi wọn ká, angẹli naa si mu Ihinrere ayọ tọ awọn oluṣọ-agutan wá, Luku 2:8-12; Iṣe Awọn Apọsteli 5:31; Isaiah 52:7

2 Ọpọlọpọ Ogun Ọrun si pẹlu wọn ni yinyin Ọlọrun, Luku 2:13, 14; Ifihan 19:6

3 Nigba ti awọn angẹli naa pada si Ọrun, awọn oluṣọ-agutan lọ taara si Bẹtlẹhẹmu, Luku 2:15

4 Wọn ri Maria ati Josẹfu ati Ọmọ-ọwọ́ naa, o dubulẹ ninu ibujẹ ẹran, Luku 2:16

5 Awọn oluṣọ-agutan n royin awọn nnkan iyanu wọnni ti wọn ti ri ti wọn si ti gbọ́ kaakiri, Luku 2:17-20

**III Awọn Amoye ati Irawọ Naa**

1 Awọn amoye lati ìha ila-oorùn wá si Jerusalẹmu, wọn n tẹle irawọ Jesu, Matteu 2:1-7; Numeri 24:17

2 Nigba ti awọn amoye ri i pe Bẹtlẹhẹmu ni a ti bi Jesu, wọn mura lati lọ si ilu naa, ati lẹẹkan si i wọn ri irawọ Rẹ̀, Matteu 2:8-10

3 Jesu Olugbala ni ẹni ti awọn amoye wá fi ori balẹ fún, Matteu 2:11; 14:33; Orin Dafidi 95:6

4 Nipa ikilọ lati ọdọ Ọlorun, awon amoye gba ọ̀na miiran lọ si ilu wọn, Josẹfu si mu Jesu ọmọ-ọwọ́, ati Maria lọ si Egipti, Matteu 2:12-15; Hosea 11:1

5 Hẹrọdu ranṣẹ, o si pa gbogbo awon ọmọ ti o wà ni agbegbe Bẹtlẹhẹmu, lati ọmọ ọdun meji wá si isalẹ, Matteu 2:16-18; Jeremiah 31:15

6 Ẹbí Mimọ́ naa pada si ilẹ Israẹli ati Nasarẹti lẹyin ikú Hẹrọdu, Matteu 2:19-23; Johannu 1:45, 46

ALAYE

**Messia Ti A Ṣeleri**

Bi a ti n ṣe ajọyọ Keresimesi alarinrin yii, o yẹ ki a ronu lé awọn ìṣẹlẹ ti o mu ki Keresimesi yii ṣeeṣe. Ronu lé Ẹbun ailẹgbẹ ti Ọlọrun fi fun eniyan. "Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẹ̃ gẹ, ti o fi Ọmọ bibi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni iye ainipẹkun" (Johannu 3:16).

Fun ọpọlọpọ ọgọrun ọdun ni awọn eniyan Ọlorun ti n reti Messia ti a ṣeleri fun wọn. Nisisiyii ni oru ọjọ Keresimesi kin-in-ni yii ireti wọn di ohun ti o daju, ati pẹlu ayẹyẹ ologo ti o yẹ fun Ọmọ Ọlọrun, Jesu wá si ayé ni àwọ eniyan, lati bá eniyan gbé. Bẹẹni, Jesu ni Ẹbun Ọlọrun fun araye, ṣugbọn O wá tifẹtifẹ lati san gbese ìrapada eniyan. Jesu mọ̀ pe Agbelebu n duro de Oun lopin irin-ajo Rẹ̀ ninu ayé, ṣugbọn ifẹ kanṣoṣo ti o wà lọkàn Rẹ̀ ni lati ṣe ifẹ Baba Rẹ̀. Ohun kanṣoṣo ni Ọlọrun n fẹ lọwọ wa fun ifẹ ti O fihàn fun wa: on ni pe ki a sin Oun, ki a si fẹran Oun. Jesu fi ayé Rẹ̀ fun wa. Njẹ kò yẹ ki a fi igbesi-ayé wa fun Un pẹlu ọkàn imoore?

**Ihinrere Ayọ̀**

Ohun nla ṣẹlẹ nigba ti a bi Olugbala tobẹẹ ti Ọlọrun fi rán angẹli lati Ọrun wá lati kede ihin ayọ̀ yii. A kò rán angẹli naa si aarin awọn ilu nla ti awọn Ju; a rán an si awọn onirẹlẹ oluṣọ-agutan ti o wà lori oke Judea. Laisi aniani awọn eniyan ti ọkàn wọn ṣipaya wọnyii ni ifẹ si Ọlọrun ati ireti ninu

ọkàn wọn fun imuṣẹ Ọrọ Ọlọrun. Lojiji, ni ìṣọ oru, ogo Oluwa tàn yí wọn ká lati ila-oorùn. Ẹru bà wọ́n nitori iran ologo yii, ṣugbọn angẹli naa wà nibẹ lati tù wọn ninu ati lati ki wọn layà. Iroyin ti angẹli naa mú wá ki i ṣe ti ibẹru; iroyin ayọ̀ nla ni: "Nitori a bi Olugbala fun nyin loni ni ilu Dafidi, ti iṣe Kristi Oluwa" (Luku 2:11). Bi o tilẹ jẹ pe awọn oluṣọ-agutan ni a sọ ọrọ yii si, sibẹ fun gbogbo agbaye ni ihin ayọ̀ yii wà fun. Bayi ni Ọlọrun pa a laṣẹ. O sọ fun awọn eniyan diẹ, O si fi aṣẹ fun wọn lati jade lọ ati lati sọ awọn ohun wọnni ti wọn ti ri ati eyi ti wọn ti gbọ́.

**Òru Iyanu**

Dajudaju òru iyanu ni fun ayé, òru Keresimesi kin-in-ni nigba ti a bi Jesu! Awọn angẹli Ọlọrun kò le ṣai mọ bi òru naa ti ṣe pataki tó; nitori gẹrẹ ti ihin ayọ̀ naa di mimọ̀, ọpọlọpọ Ogun Ọrun yọ si angẹli naa, wọn n yin Ọlọrun. Gbogbo wọn n yin Ọlọrun ni ohun kan ni idọgba pẹlu ohun ti angẹli nì ti wi: "Ogo ni fun Ọlọrun loke ọrun, ati li aiye alafia, ifẹ inu rere si enia" (Luku 2:14).

Awọn oluṣọ-agutan kò ṣiyemeji ikede iyanu yii nitori wọn ri ogo ti o tẹle e. Lẹyin ti awọn angẹli naa ti pada si Ọrun, awọn oluṣọ-agutan naa wi fun ara wọn pe, "Ẹ jẹ ki a lọ tàra si Bẹtlẹhẹmu, ki a le ri ohun ti o ṣẹ, ti Oluwa fihàn fun wa." Wọn si wá lọgan, wọn si ri Maria, ati Josẹfu, ati Ọmọ-ọwọ naa, o dubulẹ ninu ibujẹ-ẹran, gẹgẹ bi angẹli Oluwa ti wi. Ipo irẹlẹ ti wọn ba Jesu ki yoo mi igbagbọ́ wọn rárá: "Nigbati nwọn si ti ri i, nwọn sọ ohun ti a ti wi fun wọn nipa ti ọmọ yi. Ẹnu si yà gbogbo awọn ti o gbọ́ si nkan wọnyi, ti a ti wi fun wọn lati ọdọ awọn oluṣọ-agutan wá!" A! iba ti dara to lọjọ oni bi awọn eniyan bá le ni ifẹ ati ri Jesu, gẹgẹ bi awọn oluṣọ-agutan wọnyii, ati ki wọn si le lọ si gbogbo ayé lati sọ iran ti wọn ti ri!

**Ilu Dafidi**

A bi Jesu ni Bẹtlẹhẹmu, gẹgẹ bi wolii nì ti sọ ni bi ẹẹdẹgbẹrin ọdun ṣaaju akoko ibi Rẹ̀. A bi Ọba Dafidi ni ilu Bẹtlẹhẹmu pẹlu; nigba ti o si ṣe orukọ ti a n pe ilu yii ni Ilu Dafidi. Nihin ni Dafidi n gbé ti o si n tọju awọn agutan baba rẹ̀ ki a to yàn án ni ọba ni Israẹli. Wo bi o ti ba a mu to ti Jesu Ọmọ Dafidi gẹgẹ bi iran, ni lati jẹ́ ẹni ti a bi ni ilu kanna, wá di Oluṣọ-Agutan gbogbo agutan Ọlọrun ati Ọba gbogbo awọn ẹni irapada. Itumọ Bẹtlẹhẹmu ni "Ile ounjẹ." Njẹ eyi kò ha fi hàn pe ibi ti o yẹ ki a bi I gan an ni eyi - ẹni ti i ṣe "onjẹ iye ni ti o ti ọrun sọkalẹ wá" (Johannu 6:51).

Maria, iya Jesu, jẹ́ obinrin ara Nasarẹti, ilu Galili ni iha ariwa Bẹtlẹhẹmu. Bawo ni o ṣe jẹ, nigba naa, ti a fi bi Jesu ni Bẹtlẹhẹmu? O dabi ẹni pe Ọlọrun mú ki gbogbo ayé rin irin-ajo nla lati mu asọtẹlẹ Rẹ̀ ṣẹ. Aṣẹ jade lati ọdọ Kesari Augustu pe ki a kọ orukọ gbogbo aye sinu iwe fun owo-ode, olukuluku si ilu ara rẹ̀. Josẹfu ati Maria goke lati Nasarẹti lọ si Bẹtlẹhẹmu (Nitoripe iran ati idile Dafidi ni i ṣe) "lati kọ orukọ rẹ̀, pẹlu Maria aya rẹ̀ afẹsọna". Oluwa jẹri si i laisi tabi-tabi pe Jesu jẹ́ iran ati idile Dafidi, gẹgẹ bi Iwe Mimọ́ ti wi pe Oun yoo jẹ́.

**Simeoni Ati Anna**

Awọn oluṣọ-agutan ni ẹni ti o kọ́ gbọ́ ti o si kọ ri awọn ohun ologo nipa Kristi. Ninu Tẹmpili ni ogoji ọjọ lẹyin naa, Simeoni ati Anna bá gbogbo awọn ti o wà nibẹ sọrọ nipasẹ Ẹmi Mimọ́ nipa igbala ati irapada Ọlọrun ti o farahàn ninu Ọmọ yii. A le maa rò pe o yẹ ki awọn ọrọ iṣipaya yii mu diẹ ninu awọn olugbe Jerusalẹmu sọji si iran ti o wà niwaju wọn; ṣugbọn o dabi ẹni pe kò si ohun ti o le sọ awọn eniyan wọnyii ji, nitori pe nigba ti awọn amoye de Jerusalẹmu, kò si ẹnikan ninu wọn ti o dabi ẹni pe o mọ̀ nipa ibi Jesu.

**Ibẹwo Awọn Amoye**

Akoko diẹ ti kọja lẹyin ibi Jesu ki o to di pe awọn amoye lati Ila-Oorùn de Jerusalẹmu lati wá ri Ọba naa. Wọn ri irawọ Bẹtlẹhẹmu loru ọjọ naa gan an ti a bi Jesu, laisi aniani wọn bẹrẹ irin-ajo wọn lọ sọdọ Rẹ̀ laifi akoko ṣofo. O dabi ẹni pe wọn mọ ohun ti irawọ yii jẹ́, boya gẹgẹ bi asọtẹlẹ Balaamu si ọba Moabu ni nnkan bi ẹgbeje ọdun sẹyin. "Irawọ kan yio ti inu Jakọbu jade wá, ọpa-alade kan yio si ti inu Israẹli dide" (Numeri 24:17).

Idaniloju fẹrẹ wà ninu ọ̀rọ yii pe awọn amoye naa jẹ Keferi ati pe wọn ki i ṣe ọlọtọ̀ ilu Israẹli. Orilẹ-ede wọn jinna réré si ibi ti a gbé ti bi Jesu, wọn tilẹ le wi pe, "Bi a ba bi iru Ọmọ-Alade ati Olugbala bẹẹ, a o gbọ́ nipa Rẹ̀ laipẹ ni ilu wa, nigba naa ni a o ri àye tó lati foribalẹ fun Un." Ṣugbọn erò lati duro fun igba diẹ ki wọn to wá ri Jesu kò si ninu ọkàn awọn amoye wọnyii, nitori wọn ni itara lati lọ bu ọlá fun Un, eyi ni o mú ki wọn mu ọna wọn pọ̀n lọ si ilẹ Israẹli lati lọ ri Ọba ati lati fi ẹbun wọn fun Un.

**Titẹle Irawọ**

A ko le ṣaika awọn eniyan wọnyii yẹ si ọlọgbọn. Wọn ri irawọ Jesu, wọn dide, wọn si tẹle e titi dé orisun rẹ̀. Awọn ti o ba ni ifẹ ati ri Jesu ati lati mọ Ọ lotitọ ati lododo, wọn ki yoo duro titi Jesu yoo fi maa kọja lọ, ṣugbọn wọn yoo dide, wọn yoo si wa A kiri. Awọn ti o n fi tinu-tinu wá Ọba Ogo yoo ri Imọlẹ ti yoo tọ́ wọn lọ si opin irin ajo wọn.

Laisi ani-ani awọn amọye naa rò pe wọn yoo ba a ti gbogbo awọn olugbe Jerusalẹmu yoo maa sin Ọba titun naa ti a bi, ṣugbọn ibeere wọn pe, "Nibo li ẹniti a bi ti iṣe Ọba awọn Ju wà?" mú ki ara Hẹrọdu má lelẹ ati gbogbo ara Jerusalẹmu pẹlu rẹ̀. Hẹrọdu pe awọn olori alufaa ati akọwe lati wadii ibi ti a o gbé bi Kristi. Wére ni awọn olori alufaa ati awọn akọwe ti fesi si ibeere ọba, nitori pe wọn mọ asọtẹlẹ Mika: "Ati iwọ Bẹtlẹhẹmu Efrata; bi iwọ ti jẹ kekere lãrin awọn ẹgbẹgbẹ̀run Juda, ninu rẹ ni ẹniti yio jẹ olori ni Israẹli yio ti jade tọ̀ mi wá; ijade lọ rẹ̀ si jẹ lati igbãni, lati aiyeraiye" (Mika 5:2).

Ni gbogbo ọjọ ayé wọn ni awọn olori alufaa ati awọn akọwe ti fi kọ́ Ọrọ Ọlọrun: wọn tilẹ le ti kọ́ pupọ ẹsẹ sori; sibẹ wọn kuna lati mọ ọjọ ibẹwo Kristi; nitori naa gbogbo itara wọn ati ireti wọn nipa ti nnkan ti Ọrun ṣegbe. "Iwe a mã pani, ṣugbọn ẹmi a mã sọni di ãye" (2 Kọrinti 3:6). Mimọ̀ Ọrọ Ọlọrun sori nikan ki yoo gba ẹnikẹni là. A gbọdọ kọ Ọrọ naa sinu ọkàn pẹlu, eyi ni Kristi wá ṣe.

**Lilọ Si Bẹlẹhẹmu**

Hẹrọdu rán awọn amoye naa lọ si Bẹtlẹhẹmu, pe, "Ẹ lọ iwadi ti ọmọ-ọwọ na lẹsẹlẹsọ; nigbati ẹnyin ba si ri i, ẹ pada wá isọ fun mi, ki emi ki o le wá iforibalẹ fun u pẹlu." Irawọ ti wọn ti ri ni Ila-oorun tun fi ara hàn, wọn si tẹle e titi de ibi ti Ọmọ-ọwọ naa gbé wà. "Nigbati nwọn si wọ̀ ile, nwọn ri ọmọ-ọwọ na pẹlu Maria iya rẹ̀, nwọn wolẹ, nwọn si foribalẹ fun u: nigbati nwọn si tú iṣura wọn, nwọn ta a lọrẹ wura, ati turari, ati ojia" (Matteu 2:11).

Awọn amoye naa kò pada si Jerusalẹmu gẹgẹ bi Hẹrọdu ti palaṣẹ fun wọn, nitori Ọlọrun kilọ fun wọn loju àlá pe ki wọn gba ọ̀na miiran lọ si ilu wọn. Nigba ti awọn amoye naa si ti lọ, Oluwa yọ si Josẹfu ni oju àlá, wi pe: "Dide, gbé ọmọ-ọwọ na pẹlu iya rẹ̀, ki o si sálọ si Egipti, ki iwọ ki o si gbé ibẹ̀ titi emi o fi sọ fun ọ; nitori Hẹrọdu yio wá ọmọ-ọwọ́ na lati pa a" (Matteu 2:13). Hẹrọdu kò ni ọkàn lati sin Jesu: ero rẹ̀ ni lati pa Ọmọ Ọlọrun nitori awọn amoye ti pe E ni Ọba awọn Ju.

**Jesu Ti Nasarẹti**

Lẹyin ikú Hẹrọdu, angẹli Oluwa fara hàn Josẹfu loju àlá, ni Egipti, lati sọ fun un pe kò sewu bi Ẹbi Mimọ́ naa bá pada lọ si ilẹ Israẹli. Ṣugbọn ẹ̀ru ba Josẹfu lati lọ si Judea nitori pe Arkelau ọmọ Hẹrọdu n jọba nibẹ. Pẹlu itọni lati ọdọ Ọlọrun, wọn tun mu ọ̀na wọn pọ̀n lọ si Galili, wọn si wá si Ilu Nasarẹti.

Jesu ti Nasarẹti di okuta idigbolu fun awọn Ju, nitori wọn wi pe "Ohun rere kan ha le ti Nasarẹti jade?" (Johannu 1:46). Idahun ni pe, "Wá wò o." Bi o kò ri Jesu, iwọ kò le mọ riri ẹni ti Oun i ṣe, o ni lati mọ Jesu ki o to le fẹran Rẹ̀. Awọn ti o mọ̀ Ọ, ti wọn si fẹran Rẹ̀ ni o ni iṣura ti o tobi julọ ninu ayé, awọn ni o si ni ileri ayé ti n bọ̀.

**"Nigba ti onirẹlẹ ara Nasarẹti**
**Tọrun wa lati gba mi,**
**O fi ayọ nla kun ọkan mi,**
**Oru kọja lọ, imọlẹ si de."**

**AWỌN IBEERE**

1 Ta ni o kọ́ kede ayọ̀ nla ti ibi Jesu? Awọn wo ni o kọ́ gbọ́ ihinrere ayọ̀ naa?

2 Nibo ni Ọmọ Ọlọrun dubulẹ si nigba ti awọn oluṣọ-agutan wá sọdọ Rẹ̀? Njẹ a kò le ri ibi ti o dara jù bayii lọ fun Jesu?

3 Ninu ilu wo ni a gbé bí Jesu? Sọ bi eyi ti ṣẹlẹ.

4 Ki ni orukọ "Bẹtlẹhẹmu" duro fun?

5 Ta ni awọn amoye? Njẹ Ọmọ Israẹli ni wọn bi?
6 Ki ni o mu wọn wá si Jerusalẹmu?
7 Ki ni ṣe ti Josẹfu fi mu Ẹbi Mimọ́ naa lọ si Egipti?
8 Ilu wo ni Israẹli ni wọn lọ nigba ti wọn pada bọ̀ lati Egipti?
9 Ki ni ẹ̀bun Keresimesi ti o ga julọ ti a ti i fifun eniyan ri?